ELETI OFE
A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

**IJAFARA LEWU**

Olulu Asiko ti bere nisisiyi, nitorina, ki enyin abiyamo mase fi omonyin jafara.

Ki Olorun Oba ma fi iso re so gbogbo wa o.
Amin.

## Akiyesi Pataki

A fiwe yi se ikede si awon Asoju iwe irohin Eleti Ofe kakiri agbaiye wipe, enkeni ti ko ba fi owo ti o ti je ranse si wa, ao pe lejo, ako si ni fi iwe irohin ranse si embe mo.

VOL. XI No. 632. LAGOS. SATURDAY, JULY 11,—JULY 17, 1959. KOBO MEJI (2d)

# Malam Sulu Gambari We Lawani Oye, O J'oba Ilorin.

ILORIN. Irohin kan wa lati ilu Ilorin wipe, Balogun Gambari, Balogun Ajikobi Balogun Alanamu ati Balogun Kara, ti nwon je ijoye Afobaje ni Ilorin ati gbogbo awon ijoye ti o lenu ninu oba yiyan lo ti panupo fi se okan, nwon yan Malam Sulu Gambari ti idile Abudu Salami ni oba ilu Ilorin.

Nigbati awon oniwe bere lowo Alhaji Sule Maito wipe ese ti ko fi da si oro oba Ilorin yi, o dahun wipe, enitì a nfe lati sunje ko nya ina. Iba se wipe okan ninu awon omo egbe Action Group ti da si oro oba yi ni, o daju pe oro na ko ni rogbo bayi.

Orisirisi awon elere lo ti wo ilu Ilorin wa fun awuye wuye ti lawani ti nwon we fun Malam Sulu Gambari gegebi Oba Ilorin, awon Alagere, awon Oniwaka awon Olokiti awon Onirara awon Alagbe, a si tun gbo wipe nwon yio fi esin dara ni gbalasa oja oba fun iwuye Oba na.

## Ifi Owo Sowopo Nsise Fun Gbogbo Agbaiye

Ni asiko kan ni jamba ma nsele larin agbami okun tobe ti o fi je wipe, awon ti o ba nwo oko oju omi nfi ara won wu-ewu, nitoripe, oko na le fi ori so apata.

Larin ewu ti o ti koja lana, ati alafia ti a nje loni, ko nse ogbon ti wipe, a mo oko ni kikan ni kan bi kose ifowosowopo ti a ni larin awon ori le ede, lati fi ona kan lele ti yio ye gbogbo wa lati fi gba emi la larin agbami okun.

Okan ninu ifowo-sowopo be, ni ile giga gogoro kan ti a ko si eti okun (Light House) awon ina nwonyi lo nse amona ti o si ndabo bo awon oko oju omi larin agbami rere ninu okun.

Ekeji. Ninu ifowo-sowopo be ni, awon amona ti a gbe ju si arin omi lati ma fi ona han awon oko apa ibi ti o jin ati ibiti o je oke, ati apa ibiti o ye ki oko gba.

Ni odun 1882 ni igbimo gbogbo aiye fohun-sokan si iru ona ti a ngba fi dabobo oko loni tobe ti o fi je pe ko silu ti oko kole de lorile aiye loni.

## Ejo Ase'yun De Kotu

IKEJA. Odomode kan ti nse ise labe Post Office ti o nje Godwin, ni nwon fi sun esun wipe o fun ore re obinrin ti o ni oyun fun ni egbogi lati fi se oyun na, oruko ore re na nje Omeba.

Ogbeni Obiora, eniti Omeba ngbe odo re rojo bayi pe, ninu osu March tokoja, ni on sakiyesi pe Omeba nru, kini ohun ti o de si o ?.
O dahun pe, igbe orin lo nyo on lenu.
ON ranse si DR. Mabayoje pe ki o ba on ye omo na wo, Dokiti lo so fun on pe nse ni omo na loyun, nigbati on yio fi pada dele, Omeba ti jade nile.

Enikan so pe on ri igo egbogi lowo Omeba, tani fun o ?
O si dahun pe, eni ti o fun on loyun ni.

Omeba so wipe, ohun so fa a ti on fi loyun fun Godwin ni pe, o seleri lati fi on se iyawo sugbon odaran na ko wipe on ko fun Omeba ni egbogi lati fi se'yun.
Ni adajo ba ye ejo re si igbamiran.

## Oba Fi Ogundimu Je Oye Oloto

**Eko— Seranwo gbe boroki nijeta nigbati awon ebi** Oloye Oloto fi Ogbeni Ogundimu je oye Oloto ebi nidi iya ati idi baba ni kilo-subu te awon, gbogbo won lo da aso. A gbo wipe Ogundimu ni oruko Oloye titun na, ni agbole Agodogba ni nwon ti yan a.

Nigbati nwon yan a tan, ni nwon mu lo si Ipebi ninu ile Oloye Olumegbon latt ibe ni Oloye Eletu Odibo ti lo mu Oloye titun na lo kanse ni Enu-Owa, otun nkanse loja Olobun, nigbati o kuro nibe lotun lo kanse ni Agodo nibiti awon ijoye Eko gbe joko si.

Die ti a le daruko ninu awon Oloye na ni Eletu Odibo, Onilegbale, Olorogun Adodo Asogbon Onitolo, Olumegbon Kosoko Oloja Ereko, ati opo ijoye ti a ko le daruko tan.

Nigbati Oloye titun na kuro nibe, o lo yile fun Alaiyeluwa Oba Adele Keji. Die ninu awon gbajumo ti o wa sibe ni J.M. Johnson Macween S.A. Abudu, Tijani Asogbon, Saaka Soguntro, Olorun ni Ologun ati ogunlogo awon enia ti a kole daruko tan.



**Oloye Eletu Odibo**

Eniti a nwo yi ni Ogbeni Amusa Gbadesere ti o joye Eletu Odibo, on lo mu Ogbeni Ogundimu ti nwon fi je oye Oloto ilu Oto, leti ile oko ile (Railway) ni Iddo, lo kanse si Enu-owa, Oju Olobun, ti o si tun mu lo han Oba. Oye na a mori o.

## OMIRAN ILE NIGERIA DI OLOGBE

AROCHUKU. Omiran kan soso ti a ni nile Nigeria ti oruko re nje Alakuku ni a gbo wipe o salaisi. Opolopo

(Wo yeku loju ewe keji)

## Aw n Omo Akeko Nilu Oyinbo



Ogunlogo nínú awọn ọmọ wa nílu Nigeria l o l ọ kọ iṣẹ ọwọ ati iṣẹ ọgbọn ori ni Royal College of Science ati Technology nilu Glasgow.

Awọn ti a nwo wọnyi jẹ diẹ ninu awọn ọmọ akẹkọ ti o wa lati orisiṣi ilu, lati kọ iṣẹ nile ẹkọ na ti a fi adọtalengba okẹ pọun kọ fun ilọsiwaju a t i idagbasoke awọn orilẹ ede.

Ninu awọn t i a nwo ninu aworan yi ni ọmọ ilẹ Nigeria kan wa, ti a npe ni Ọgbẹni Babatunde Adekunle Ọlanrewaju Fisher, ọmọ ilu Eko, on lo mbẹ lapa osi, o nkọ iṣẹ Civil Engineering.



# Nigerian Ports Authority

## INVITATION TO TENDER

Tenders are invited for the provision of catering facilities at the Atlantic Terminal, Apapa Quays, on the days of arrival and departure of mailboats, for a period of three years commencing on 1st August, 1959.

Tender documents, giving details of the services to be provided and setting out the general conditions of the contract may be obtained from the Secretary to the Authority, Nigerian Ports Authority, 216, Broad Street, Lagos, on deposit of the sum of £5 which shall be returned by the Authority on receipt of a bona fide tender.

The deposit of £5 should be made to the Cashier, Accounts Department, Marina Offices, Lagos (opposite the Lagos/Apapa Ferry Wharf).

Tenders should be enclosed in sealed envelopes marked " CONFIDENTIAL ATLANTIC TERMINAL CATERING " and forwarded to the undersigned so as to reach him not later than NOON, Friday, 17th July, 1959

The Authority is not bound to accept any tender.

A. R. CORDON
Secretary to the Authority

N. P. A Notice No. 310.
Date 6th July, 1959.


### EGBE SERAFU ATI KERUBU SE NKAN ARA

Ọrọ ko dun nigbati awọn ọmọ ẹgbẹ Serafu ati Kerubu se ajọdun ọdun kewa ti ẹnikan kan Ologbe Iyafin Victoria Ibidun Dagunduro ti fi ile aiye sile nilu Ilesha.

Ki o mu wa wo awọn ọmọ egbe serafu ti gbogbo won funfun balawu, ti won si fi ara jọ awọn angeli, gbogbo awọn Olorisa Oko ti o mbẹ nilu Ilesha ko si eyiti o le jade lo'o na, nitoripe aso funfun je ara won lọ.

Ologbe ti o ku na je ọkan pataki ninu egbe Aladura, o si mbẹ ninu ẹgbẹ Ayaba Esther.

Lojo ti a wa yi, nse ni gbogbo ara awọn ọmọ egbe Serafu eko mona mona, abela ti awọn tan lojo na le ni egberun.

Aṣiwaju won na ni Leader Makinde nibi orin nse yungba. Orisirisi amure, yellow funfun pupa ati Blue.

Enyin egbe Serafu, ehin iya na a dara.

Ati Aladura, ati Akọrin, Agbagba meji, Eto Dafidi, eto Joshua, Ayaba Esther, Dorcas gbogbo won dabi ọmọ iya Kanna




AVAILABLE AT:-
AKOSHILE BROTHERS
5, BALOGUN STREET WEST.
P.O. BOX 599. LAGOS.

## Oluwadi Oko Ofurufu



Ęniti a nwo ninu aworan y i n i Ọgbẹni S i r Edward ullard F. R. S., on ni a yan gẹgẹbi Alaga ẹgbẹ awọn ti yio ṣe iwadi nipa o o ofurufu t i yio ma wo oju ọrun lọ, eyiti Ọgbẹni Harold Mcmillan fẹ da silẹ nilu Gẹsi laipẹ yi.

## Afi Fila P'ekun Ojo Kansoso N i Iyi Re Mo

(APA 5)

**Nigbati Afifila Pẹkun kuro ni ile Ọba lọjọ na gbogbo enia tẹle lẹhin, nwọn sin lọ sile rẹ. Iwọn ọgọrun obinrin ṣeleri lati fi ṣe ọkọ lọjọ na. Ọjọ na minringindin fun u.**

**Nigbati ilẹ ṣu olukuluku enia si pada sile rẹ, Afi-fila p'ẹkun lero pe bi ilẹ ba ti mọ awọn Onilu ni yio wa ji on lori ẹni. Ṣugbọn ko ri bẹ rara, Olukuluku enia bẹrẹ si fa ọmọ rẹ leti wipe, Hunin ! nibo ni o nlọ? Bi ọ ba lọ jẹki okunrin Olo-ogun yọo ju atare lu ọ, egele gbe ọ.**

**Latigba na wa, ẹnikẹni ti o ba ti foju kan Afi-fila p'ẹkun ni orere, nṣe ni oluwa rẹ yio ṣena gba. Bayi ni o di arisa ina, a ko ya ibi si gbogbo enia.**

**Bi ọba papa ba ti gbọ pe Afi fila-pẹkun de, yio wipe ki nwọn sọ fun pe on sun. Nigbati o ri pe kaka ki on ma gba iyi siwaju, abuku ni awọn enia fi nkan on, o wa lọ yẹwo lọdọ Babawo kan ẹniti o kifa fun bayi pe:-**

**Afi-fila p'ẹkun ọjọ k a n ni iyi rẹ mọ a difa f u n Ọjọmu lọjọ ti o nlọ sojo Ogun, ti ẹkun yio ma da wọn lamu.**

**Bayi ni Ọkunrin Afi-fila-Pẹkun di ẹni ẹtẹ ati abuku arin ilu.**

## Odaran Be Adajo K'o F'oju Anu Wo On!

IBADAN Ọkunrin alagba kan ti o dagba to enia odun marun diladọta ti orukọ re nje Isamọtu Yamusa, ni a gbọ wipe o se afọwọra owo ijọba ibile Iwo (District Council) bi Pọun merin leladorin l e legbeta ati sile merinla.

Nigbati adajọ bere lọwọ rẹ pe, o jẹbi tabi ko jẹbi, o dahun pe on ko jebi.

Nigbati ọdaran ri pe, oro na de oju ogbgade , tabi ko si adajo na ni laii je on niya, gbo oro ti o sele larin odaran na ati adajo.

Odaran. Jowo, oluwa mi, mo bebe lodo re, sanu fun mi, ki o si se mi gegebi baba re.
Adajo. Beni! o ye be ni toto, sugbon iwo ko ba ti tete je wo obun, ki a si da aso bo o.

A ti mo pe, ko si eni ti ko le ri adanwo, sugbon oluware nilati ranti wipe, on ni ebi, iyawo, ati awon omo were ki o to se ohun kan, sugbon iwo ko tete jewo, o si ba ejo re de walalalina

Odaran. Sugbon, kiyesi alagba e le sakiyesi ojo ori mi.

Nigbati Adajo so fun pe, ewo odun gboro ni on ti lero lati jusi, ni tori ki o ba le ko ise ti yio se jeun.

Odaian. n a dahun wipe, tele-tele on ti k o ise Dereba (Driver).

Adajo dahun pe, bi on ba jeki odaran na lo laifaragba, awon olosa ni yio ma fi moto ko

kakiri, nitorna on ko ni s e anu fun o tun le wa ba on mhin Adajo ni ki o se ewon odun merin.

## ADAJO SO AGBEJO MO OLUKO ILEWE NIDI

IKEJA. Adajo kotu Ikeja lo so agbeje mọ ọdọmọkunrin kan nidi ti o jẹ ọkan ninu awọn oluko ilewe giga ti New Nigeria High School ni Mushin,, wipe ko gbodo ja de ipo ti oro re yio fi de kotu, fun oṣu mejila Oruko oluko ilewe na ni Adio Ṣolanke.

Esun ti awon olopa ka mo lesẹ ni wipe, o yaju si okunrin kan ti o lo woran ere bobo afẹsẹgba ninu ogba New Nigerian H gh School ni Mushin, o si tun paṣẹ fun awon omo akeko rẹ wipe ki nwon lu u. Oruko ẹniti nwon na ni Karibi Anabraba.

Awon omo Akẹko si lu okunrin Karibi na ni alubolẹ tobẹ ti oju re fi be. Agbo wipe olopa mu Karibi lo si ile Alaisan Orthopaedic fun iwosan Adajo ro oro oluko na siwa, sẹhin, lo ba so agbejẹ mo nidi.

## JAMBA MOTO ṢELẸ LỌNA ABOKO

**OKE-ỌYA. A gbọ irohin wipe moto akero kan ti o gba ero tan, ti o si nlọ si Ibuba Dereba ati ẹniti o ni ọkọ na joko niwaju.**

**Bi awọn ti mbẹ lori ere lọna ajo won, nwon ba moto kan niwaju, nwon si nfẹ sare koja re lo: lojiji ni owo rẹ ju tobẹ ti moto na fi takiti o si gbina, ina na lo si jo Dereba ati Onimoto pa.**

(Wo yoku loju ewe kerin)

## OBINRIN GBA OYE TI OBINRIN KO GBA RI

**A r i gbo wipe Iyafin Abimbola Silva ti o lo ko ise isegun lona t i Oyinbo nilu Oyinbo, o si gba oye D.P.H. ninu idanwo re oye ti o je wipe, a koiti r i obinrin egbe rẹ kan ti o yege ninu iru idanwo be ri.**

**Ninu osu to koja lo yi ni Iyafin ti a wi yi lo se idanwo na ninu ile Alaisan ti** University College o si t i ibe wa yege, o si gba oye S.R.N.

Arabinrin na ti woko nilu Oyinbo o tibo wa sile.

E MA KA
IWE IROHIN
ELETI-OFE
LỌSỌSẸ
TI O KUN FUN
IROHIN ALADUN

# ELETI - OFE

A-NJU-WỌN KO ṢE WI L'ẸJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM

28, Kosoko Street, Lagos. "ELETI - ỌFẸ LAGOS"

P O Box 467 Phone 23370

VOL. XI. NO. 632 SATURDAY JULY 11 - JULY 17, 1959


## E SORA NAWO

Wosika wa ose yi ti a fi se aṣayan ọrọ wa fun ẹnyin okawe wa ni imoran lori owo nina, gegebi owo ti jẹ ohun ti o dabi eye ti o gun'ye ti o si nfo bi a ko ba tọju re sinu ile (Cage) to paramọ daradara.

O yẹ ki olukuluku wa mọ wipe owo, ape kanu ko, lẹ orisa kan ti o fe itoju pupọ, ti Ọlọrun ba dari rẹ sọdọ enikan, ki enibe mase ma na owo na ni inakuna tabi ki oluwarẹ mase ni ifokanbale wipe on ti goke agba nuni, ko tun si ewu airowo na fun on mọ.

Ọrọ ti owo kuro ni nkan ti enia le ka kun ohun ti ko le tan lọwọ eni nitoripe, eiye ni owo, ẹniti Ẹlẹda ba dari re si lẹdo ni yio ba si ile oluware. Ẹ ṣ'akiyesi awon olowo enia ti a mọ bi ọmọ oninakuna ti nwon ti lo igba tiwon ninu idẹra ati lehin idẹra ninu iponju airowo jẹun ti nwon ti rekọja lọ s'okun igbagbe.

Ọkunrin olorin kan ni o kọ orin bayi nilu Eko wayi nigba aiye rere ijọun.

Alijonnu ni Ṣile,
eni to ba ni k'oyọ mọ nba,
b'o ba le fo wa ioni, bo ba dọla
o le fo lọ. (Oiẹ kolo'gba aṣọ).
Ẹṣọra na'wo.




## Dr. Asikiwe Nilu Oyinbo



Eniti a nwo yi ni Olola Dr Azikiwe, on ni Ijoba re se adehun papo pelu awon igbimo Radio ati Television nilu Oyinbo ati Eastern Nigeria Broadcasting Coy. lati wa bere ero Television ni agbegbe Ila Orun.

## Alagbafo Kan Ku Lojiji

ABEOKUTA. Ọkunrin alagbafọ kan, ọmọ ọdun mejijdilogoji ti orukọ re nje Garuba Apena ara Igbore ni agbọ wipe, ko ṣe amodi, bẹni ko se aisan ti o fi di aṣọ rẹ ru lọ si odo nibiti o gbe nfọ aṣọ.

O fọ gbogbo aṣọ re tan lọjọ na. o di ru o si kori sile. Bi o ti nlọ loju ona pẹlu aṣọ ti o lọ fọ, lojiji ni oyi gbe, emi rẹ si rosu loju kanna nibẹ. Iru iku na ya ọpọ enia lenu.

Nwon sọ wipe bi oyi ti gbe e, ti o si subu lulẹ bẹni o na tọtan tị gbogbo egungun ara rẹ rọ ka! ka!! ka!!!

Awon ọlọpa gbe oku rẹ lọ si ile alaisan ni Abẹokuta fun ayewọ, lati mọ kini sababi tabi iru silo se iku pa alagbafọ' na. Awon ọlọpa ti tese bọ nwon nse iwadi ọrọ na lowọ.

## JAMBA MỌTO ṢELẸ LỌNA ABOKO

( O bere loju ewe keta )

Ṣugbọn ninu Mọto keji, eyiti mọto to ṣe jamba na fe gba iwaju rẹ, a gbọ wipe, ko baje pupọ, awọn enia merinla pere lo fi ara pa diẹ.

Irohin na wa lati ọdọ onirohin Ijoba ile Hausa.

A gbọ pe ọrọ na si mbẹ ni kawọ awọn Ọlọpa.

## Awon Elewon Merindilogun Ku Si Iti Yole

ROSIA. A gbo irohin wipe ina sele ninu ogba ewon kan ti a fi igi se lati owo okunrin asiwere kan ti on papaa, je elewon pelu.

Awon merindilogun ti ina na jo pa, je elewon ti nwon ti mo inu ile titi ina na fi ka won mo inu ile o si jo won pa Ogunlogo awon elewon miran ati awon Dereba lo fi ara jona ti nown si gbe lo si ile alaisan pajawiri, ti nwon da sile nitosi ibiti ina na gbe jo.

## Awọlowọ Gba Isinmi



Oloye Awolowo ti fa iwe ninu iwe yi ni a gbo, wipe o gba aye isinmi kuro lenu ise fun igba die, o si fohun sile wipe, on ko fe ki enikeni mu oro kan to on wa tabi ki enikan wa yo on lenu nibiti on gbe nsinmi.

## Oba Awon Fulani Salaisi Ni Sokoto

ṢOKOTO Irohin kan wa wipe Alhaji Ahmadu Ọba awọn Fulani ṣalaisi nilu Ṣokoto nigbati o dagba di ẹni adọta ọdun, o si jẹ ọkan pataki ninu ọmọ ẹgbẹ N.P.C.

A gbọ pe ko ju iwọn oṣu kẹta lọ nisisiyi ti nwọn yan Ologbe yi si igbimọ awọn Ọba on kanna yi ni igbimọ fun awọn ẹlẹgbẹ jẹbẹ gbo-gbo ti o mbẹ ni Ṣokoto.

Ologbe Ọba yi kọ kewu rẹ ni igboro ilu Ṣokoto, on lo si ti nṣe olutọju ile ifi-nkan pamọ si ni Ṣokoto. ninu ọdun 1927 si 1932. O si tun ṣiṣẹ akọwe ninu ile ibiti nwọn nkọ ẹkọ lọdun 1933 si 1953.

A si gbọ wipe Ọba yi gun ẹṣin lasiko ti nwọn nṣe ere Durbar fun Duke of Gloucester, ko ju iwọn ọdun mẹfa lọ nisisiyi ti a gbọ pe o joye ọba. Ọlọrun ko dẹlẹ fun u.

## FAO EXTENSION CENTRE FOR WEST AFRICA

ROME 4 July.—An agricultural extension development centre for West Africa will be held at Ibadan, Nigeria, from 7-17 July. The centre has been organized by the Food and Agriculture Organization, in co-operation with the Commission for Technical Co-operation in Africa South of the Sahara (CCTA), at the invitation of the Government of Nigeria and the University of Ibadan.

FAO officials said the meeting, first of its kind for the West African region, aims at planning future action in agricultural extension work on the basis of experience gained by other countries in their agricultural development. It was expected that about 50 delegate would attend, coming from the countries and territories of French Equatorial Africa, the Republic of Guinea, Portuguese Guinea, Sierra Leone, Liberia, Ghana, the Ivory Coast, Togo Dahomey Nigeria, Cameroons and the Belgian Congo.




## Ebun Ife Fadaka Fun Oba Akran



Eniti a nwo ninu aworan yi ni Alaiyelowa Oba Akran ti ilu Badagry, awọn eni maran wa lati Western Nigeria Cooperative Bank pelu ebun ife Fadaka lati fi ta Ọba na lọre fun iṣe ribiribi ti o ti ṣe nipa jijeki Cooperative Bank ni idagbasoke ni ipinlẹ Iwo-Oorun gegebi awọn ẹgbẹ na ti mọ riri iṣẹ rẹ ti o ti ṣe. Ọba Akran gba ife Fadaka o si dupẹ fun wọn.

## Awon Loya Yan Alaga

EKO. Ninu ipade kan ti awọn awọn loya se nilu Eko lojo Saturday to koja, ni nwọn gbe ti yan Ogbeni Ayo Williams [illegible] Ọmọ Obi ti o n se Adele ni akoko kan, ni Adele Baba egbe awọn Alaga egbe Loya.

Ologbe Alhaji Jubril Martins ti o ku ni igboro Meka ... ti [illegible] Seyikon egbe kan [illegible] yan Ọmọ Obi ni ipo Alaga.

Eniti a gbọ wipe on ni Baba egbe nigbati [illegible] awọn Loya ile Nigeria ni Ogbeni F. G. Unsworth ti o joye Attorney General nilu Eko.

Ọmọ-Obi [illegible]

ELETI-OFE D'ARABA

## Itan Ogbeni Oloke, Olowo Isale Eko

Okunrin olowo kan ti wa ni Isale Eko, ti oruko rẹ nje Oloke. Ọkunrin yi, ọrẹ ati anọ lo je fun Oloye Aṣọgbon nitorine, Ijoye na fẹ okan ninu awon ẹṣin Oloke yi.

Ni ọjọ kan ti Oloke gun ẹṣin lọ ki Oloye Aṣọgbon ninu Iga rẹ, nigbati o de ibẹ, o sọkalẹ, o so ẹṣin rẹ mọlẹ, o si wọ ile lọ ki Aṣọgbon awo rẹ. Gẹrẹ ti o wọ Iga lọ, awon ẹru Oloye Aṣọgbon tu okun ẹṣin, nwon mu lọ nwon pa, awon ti o nkun ẹṣin na okun yi, awon ti o dana ti nwon nsun gaari nsun u, bi awon ti nkun ẹṣin na, bẹni awon ti o nda bata ẹda. Ki awon ti o nkun ẹṣin to sun tan, nwon ti je gbogbo gaari tan.

Nigbati Oloke jade, ti ko ri ẹṣin rẹ, oni ha! awon ẹru Aṣọgbon ji ẹṣin on paje! Nigbati Oloye Aṣọgbon gbọ ọrọ yi, nje lo tẹ a ẹkun gbaragada, o wipe ẹnimọ Ẹni on ri yi, anọ on da ẹle mọ on. Ọpọlọpọ owo ati oli ta Oloke fi fun oju awo rẹ na. Ẹnu̇ e bi Ọba Dosunmu ba gbọ ọrọ yi, yio bínu pupọ pe Oloke da ẹle mọ Ọgagun on. Bayi ni awo Aṣọgbon gun ẹṣin wa, pe ko si fi mu poda bọ ile rẹ.

Itu iwa bayi ni awon ajagbara ma nhu nigba aiye atijọ. ṣugbon ni akoko ti wa yi, idena ti de si wa lọpọlọpọ, oyinbo si ti so aiye di ẹrọ.

Lẹhin ti gbogbo ọrọ nwonyi ṣelẹ tan, ni Oloke wa to Agarawu lọ, o ro bi gbogbo ọrọ nwonyi ti lọ fun Agarawu o si ba damoran, a ko mo bi Danmọle olorin Eko ti ṣe gbọ ọrọ yi tobẹ ti o fi f'ọrọ na korin.

Nigbati Ọba Dosunmu gbọ ọrọ orin yi, o ranṣẹ pe Oloye Aṣọgbon o si bi lere bi ọro na ti lọ. Asugbon, kọ ẹ'ọ o ro fun Ọba o si sọ nipa ohun ti ẹno rẹ fi bebẹ. Ọba ranṣẹ pe Agarawu; ṣugbon o ko lati da ba Dosunmu lohun, nipa ọro yi na ni a gbọ wipe o ṣe ikú pa Agarawu.

Nigbati Oloke gbọ nipa gbogbo ohun ti oṣẹle, o kalo kuro ni Isalẹ Eko, o si lo fi ori pamo si abẹ Oloye Kosoko o si fun ni ile ni eti osa lẹhinkule Oloye Onitolọ. Kosoko ko si gba ki ẹnikẹni ṣe e ni ibi. Adugbo ibiti o ngbe ni nwon npe ni Oloke Olowogbowo tabi Oke Olowogbowo titi di oni oloni.

Eyi na ni Bẹgbaji fun fi korin bayi pe:-

"Aiye lo pa Pinnisin (2)
"Aiye lo yo ida to fi pa agarawu.
Ẹni ba ti ṣe niga ni nwon mu lo pa.
Ti ko modi Ọpọlọpọ ti ko mọ i l'aiye ti ran t'Olodumare Aiye lo pa Pinisin


Kere o !

A ni orişirişi ogun German to şẹşẹ de, fun oniruru aisan tọkunrin tobinrin. Tete wa ra tire ki o to tan.

J. A. AJAO
BROTHERS
MEDICINE STORES
7 Egerton Road Lagos


### IKILO

A ṣe ikede yi fun gbogbo enia pe ile kan to wa ni Cole Street, Nos. 38 ati 42 ni Surulere je ti J.M. Babalọla, 45, Araille St. New Lagos.

Ẹnikẹni to ba duna-dura ilẹ na pẹlu ẹlomiran yio fi owo rẹ ṣofo, ayafi ki o wa sọdọ Ogbeni J.M. Babalọla.

Aṣẹ ni Lati ọwọ

J.M. Babalọla

## ỌBA ADELE JARE



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Alaiyeluwa Ọba Adele Keji, ti o jẹ Baba egbe fun igbimo Lagos Town Council. On ne si a gbo wipe o jare awon omo igbimo rẹ lodo Ijoba, pe owo osu rẹ ko gbodo di ku ni £2,800


OGUN ITAJA

POLOWO ỌJA RẸ
SINU IWE IROHIN
ELETI - ỌFẸ


## Odun Ileya Imale Nilu Oyinbo



Awọn obinrin Imale meji ti a nwo ninu aworan yi ni Virginia Waheed ati Sahida Ghose ara awọn obinrin Musulumi ti o ba wọn kirun ọdun Ileya ninu mọṣalaṣi Jehan ladugbo kan ti nwọn npe ni Woking ni London.

Awọn enia pọ bi omi ni ọjọ ikirun ọdun na, awọn ara ile India, ni Pakistan, ati gbogbo ilẹ Imale ti o ni enia nilu Oyinbo to fi de Afghanistan ati Sudan pelu Yemen. Ọdun na dun jọjọ.

## Omo Akeko Kan Jare Ejo Re Nilu Oyinbo.

LONDON. Odọmọkunrin kan ọmọ ile Nigeria ti ko ju ọmọ ọdun mejidogun lọ ti o lọ kọ iṣe Loya ni ilu Oyinbo, ti orukọ rẹ nje Adeniran Ayọmano, ni Onidajọ Oyinbo kan, adelebọ fi ẹjọ re sun wipe, o fi agbara ki en mọle o si ba on lo pọ.

Nigbati nwọn gbe ọrọ rẹ siwaju adajọ, adajọ yẹ ọrọ rẹ wo, tinu-tẹhin o si ripe, ọmọ akẹkọ na ko jebi, o si da a sile ki o ma lọ. Nigbakeji, awon ọlopa tun lọ mu ọmọ akẹkọ yi, ṣugbon Adajọ tun da sile ki o ma lọ, nitori ẹnu awon Juri ko sekan.

Lori ekẹta ti awon Ọlopa tun lọ mu ọmọ akẹkọ na lọ si kotu Ọdaran ni Old Bailey nilu London. Obinrin na rojọ wipe Ayomanor ti a wi yi, lo ni ile ti on ọkọ o n ati ọ m ọ ngbe.

Adajọ ro ọrọ rẹ siwa-sẹhin, o bere lọwọ awon ọlọpa bi nwon ba ni oro lati so, nwon dahun wipe, awon ko ni oro lati so, ni adajo ba fa iwe ẹjọ na ya. Malison Ayomanor, o ku orire.

## EWU LỌ LORI AWỌN OSISẸ PUTNEY.

LONDON. A gbọ irohin wipe awon oṣiṣẹ kan nilu London ti nwon nṣe iṣẹ lọwọ ni nwọn lọ ri ẹtu oloro kan (Bomb) nibiti nwọn gbe fi kẹdẹ si pẹlu erojà rẹ wipe, bi nwọn ba sa ti fa okun rẹ, iṣẹ ni ki ina dun.

Nigbati awọn osiṣẹ kan elegba yi kiti, awon osiṣẹ na sare egungun wipe Olọrun yọ awon ti nwọn ri tele ri. Bi nwon ba lo gbe jiga ti o ba si bina, gbogbo won ni yio rasu sibẹ. Ninu ile ni nwon ri ẹtu oloro na mo, lọganjọ oru ni nwon lo kan ẹtu oloro na nibiti nwọn ri i mọ.

Etu oloro na ti nja, o si danu si ara panu ti nwọn fi bo etu na. Ara awọn ti o ti lọ si ogun ri so pe ara etu oloro ti awọn Jamani ti se ni.

Nigbati nwọn ma fi ina si etu na, igba enia ni nwon ko kuro ni agbegbe ibe, nigba ti nwọn si fina sinu etu na, ile merinla ni fere ṣe re pin si wewe sugbon ko si eni ti o fi ara sesẹ.

## Olowo Ati Ologun

Lati Owo
Y. Ade Buraimo

Awọn ọkunrin meji kan wa, ọkan jẹ Olowo, ekeji jẹ Ologun. Awọn mejeji jẹ ọre timọtimọ, korikosun ni wọn jẹ.

Ọmọ Olowo yi, nlọ si ile iwe (School) ti Ologun na nlọ bakanna.

Bi Ọmọ Olowo ba nlọ, Baba rẹ a fun ni owo lọ si ilewe (School) gẹgẹbi owo nina (Pocket money) ọmọ ti Ologun yi kosi ri owo mudani tio ba bere owo ni ọwọ baba rẹ baba rẹ aoi ko si owo, samura si iwe rẹ dada. io ba pẹ titi, owo yio de tio ba bẹre iṣẹ. Ọmọ Ologun yi wa bẹrẹ si soriko, ti ọmo Olowo yi ba bere si ra nkan jẹ ni ile iwe (school).

Lẹhinna ni o wa ba baba rẹ, oni on ko lọ si ilewe mọ o. Baba rẹ ni kini o njẹ be? Ọmọ Olowo na wa lọ ba Baba rẹ pe on na kolọ si iwe iwe mọ o. Ile itaja (Shop) ni mo fẹ maduro.

E si ti Baba Olowo yi yio fọ nipe, ko buru na, o wu emi papa alara na lati da ọ'duro Baba Ologun yi wa lọ ba ọrẹ rẹ olowo yi pe bayi, bayi, ni ọmọ on wi O ni ti on na papa sọbẹ, ko tilẹ wu mi pe ki o malọ si ilewe (School) mọ rara, kio duro kio mata ọja.

(Koṣi pari)




E MA KA
IWE IROHIN
ELETI-OFE
LỌSỌSẸ
O KUN FUN
IROHIN ALADUN

# Electricity Corporation Of Nigeria

## INVITATION TO TENDER

SWITCHBOARDS FOR THE SMALL TOWNS DEVELOPMENT PROGRAMME (CONTRACT 2S)

Tenders are invited from responsible contractors for the supply of the following items, c. i. f. Lagos: —

10 — Switchboards 10 MVA 440 volt 3 phase 4 wire containing in aggregate 25 generator panels (for controlling alternators in the range 100-290 KVA O.8 pf) 30 feeder panels 10 off load bus section isolators and 10 synchronising swing panels.

On payment of a deposit of £5 tender documents comprising tender, specifications of the contract,etc, may be obtained from, The Secretary, Electricity Corporation of Nigeria Electricity Headquarters, 13, Baord Street, Private Mail Bag 2030, Lagos.

Each tender must be enclosed in a sealed envelope marked "Confidential-Tender for the Supply of Swichboards for the Small Towns Development Programme (Contract 2 S)", and must be received at the office of the Secretary not later than noon on 8th August, 1959. Tenders received in any other manner will not be considered.

It is essential that the tendering contractor shall be in a position to produce evidence of having succefully undertaken previous contract of a similar nature.

On receipt of a bona fide tender the £5 deposits will be refunded. The Electricity Corporation of Nigeria does not undertake to accept the lowest or any tender.

Further information concerning this contract may be obtained on application to the Chief Electrical Engineer at this Headquarters.

ARTHUR FAUL
Secretary to the Corporation.





OMIRAN ILE NIGERIA
(O bere loju ewe kini)

awọn ọmọ ilewe to ti ngbọ irohin tabi itan nipa awọn omiran sugbọn awọn ko mọ bi omiran papaa ti ri tabi iru awọn enia wo ni a npe ni Omiran

Awọn ọmọ ile ẹkọ, ni agbegbe Okgiwe a ma lọ wo omiran Alakuku nibiti o gbe nro oko, tabi nibiti o nṣe ere, awọn Olukọ a ma ko awọn ọmọ ilewe lọ si Arosuku lati lọ ri omiran Alakuku.

Ni ọdun 1948, a gbo wipe omiran Alakuku bi omo okunrin kan, nigbati ọmọ na di omo oṣu mẹfa, o ti bẹrẹ si rin ṣugbon bi enia ba ri omo na, yio pe e ni omo odun mẹta.

Nigbati ọpọ awọn enia nrọ wa wo ọmọ na pupọju ni iya ọmọ na, ba gbe wa sapamọ si ọdo ẹgbọn Alakuku kan ni Enugu, gbogbo enia lo nrọ gidigidi wa wo ọmo ọdun mẹta ti o tun nmu ọyan. Iya ọmọ na ko si mọ oro fi pamọ, a ma sọ fun wọn pe, ọmọ oṣu mẹfa ni. Ogede-gede ha, ha, ha, ọmọ oṣu mẹfa lo to yi? a gbọ pe ofi ọmo meji sile laiye.

Ṣugbọn ki o to ku, ati tun ni alagbara miran ti awọn npe ni Superman, eleyi ti kọja lo si Pọta nisisiyi, koiti pada de.

ẸKỌ KEJI NI EDE HAUSA

| | |
|---|---|
| Goma Sha Daya | Mokanla |
| Goma Sha Biyu | Mejila |
| Goma Sha Uku | Mẹtala |
| Goma Sha Fudu | Mẹrinla |
| Goma Sha Biyar | Mẹdogun |
| Goma Sha Shida | Mẹrindinlogun |
| Goma Sha Bakwai | Metadinlogun |
| Ashirin Biyu Babu | Mejidinlogun |
| Ashirin Daya Babu | Mokandinlogun |
| Ashirin | Ogun |

(Koiti pari)

ASOJẸ ỌRỌ

Baba bo baba baa baa bo baa baa, ewe Opoto bo ewe Orombo awa ni yio bori won.





## Ogun Aran Ejo Inu

Aradan Worm Expeller jẹ ogun aran pataki fun ọmọde ati agba ọkunrin ati obinrin. Ra igo kan lati ya gbogbo awon aran buruku ti o nba ọ ja nitu danu. Bi o ti npa aran, bẹni o npa ẹyin wọn. Wa ra tirẹ ki o to tan. Igo kan jẹ 2/6
Owo ọkọ si jẹ 1/-
THE ẸGBA TRADING
ARADAN STORES
8, Denton Bridge Street.
P.O Box 2. Ebute Meta



RA BUREDI



TI O GBADUN JULỌ TO SI NFUN NI LOKUN INU ATI ILERA

BURẸDI "DE FACTO"

TI O LOKIKI FUN AJE GBADUN RE